E MA KA IROHIN IMOLE KI E SI MA POLOWO OJA YIN SINU RE

# IROHIN IMỌLE

MOTTO: IMỌLẸ DE, OKUNKUN PARADA.

READY FOR SALE
Iwe Arofọ ti -:
ANỌYIN LOHUNBI-ỌMỌGE- IMARO
APA KETA
LATI OWO
G. A. SOWUNMI
Price 2/-
Modupe Press
16, Bamgbose Street,
Postage Extra

VOL. I No. 37, WEDNESDAY MARCH 12, — MARCH 18, 1958 KỌBỌ KAN

## "Adetokunbo Ademola" Je Oye Adajo Agba

Latigba ti Ijoba Gesi ti nse ile Naijiria, a ko gbo ri ninu itan wipe, nwon fi enia dudu joye adajo agba silu Eko ri.

Sir Foster Sutton ni oyinbo ti o ti mbẹ ni ipo na ri, ṣugbọn enia kọ le ṣiṣẹ titi ko ma ṣe ni simi. Alagba na nilati lọ gba aye isimi lẹhin ọpọlọpọ iṣẹ Gomina agba si wa roo si ẹtọ wipe, Sir Adetokunbọ Ademọla ni ipo na tọsi, ni nwọn ba fi joye Adajọ Agba fun gbogbo ilẹ Naijiria.

Adajọ Agba yi, Sir Adetokunbọ Ademọla jẹ ọmọ bibi inu Alaiyeluwa Sir Ladapọ Ademọla, ọba Abẹokuta. A bi i ni ọjọ kini osu Feb. 1906, o bẹrẹ ẹkọ iwe rẹ ni ilewe Aguda, nigbati o pari ẹkọ rẹ tan nibẹ o tun lọ si ilewe giga Saint Gregery lati ibẹ lo ti kọja lọ si Kings College ni Eko.

O ṣiṣẹ fungba die ninu ile iṣẹ Ijọba ni Eko, nigbati o di ọdun 1927 lo kọja lọ silu Ọba lati kọ iṣẹ amofin, ni ọdun 1932 lo gba oye ribi-ribi ninu ẹkọ ofin na.

Iṣẹ lọya lo kọkọ bẹrẹ, kẹrẹ-kẹrẹ o di adajọ, bayi na loṣe titi ti o fi de ipo ti o de loni. Lọdun 1957 ni ọba Gẹsi fi oye Sir da lọla. O si gbe omidan Kofoworọla Moore ni iyawo ni ọdun 1939.

Oye a mọri o, Adetokunbọ tiwa, e ko ni ṣe e ti o.

## EWON OSU MEFA FUN Isola Aremu

Ni ọjọ aje ti iṣe ọjọ kẹwa oṣu yi ni Ọgbẹni J. B. Majẹkodunmi, Adajọ Kotu kan ni Eko ju ọdaran kan Iṣọla Arẹmu ẹni ọdun mọkandilogun sẹwọn oṣọ mẹfa nigbati o ri pe o jẹbi ẹsun wipe o ji apoti wara (Milk) kan gbe ti owo rẹ si jẹ pọun meji ṣile mẹrindinlogun ati kọbo mẹfa £2 : 16 : 6 lọwọ arabinrin onisowo kan ti oruko rẹ njẹ Mọriamọ Abikẹ ni ọjọ kẹjọ oṣu yi.

Ẹsun na nipe, arabinrin ti o nta onjẹ ni ile itaja ni Jankara ra apoti wara ti o pọ diẹ ni ṣọbu awọn k. Chellarams ni ẹhingbẹti ni Eko.

## OLOLA OLOYE OBAFEMI AWOLOWO KU IRIN

IGA ẸKẸRIN, ILARO

Mo ki oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ku abọ ipade ti o ṣe ni Ilaro, papa nipa alaye orisirisi ti ọ ṣe nipa ijọ Iwọ-orun. Odunmare ti o fi ọ ṣe aṣiwaju ko ni jẹ ki o bajẹ ni igba tirẹ. Ọrọ rẹ nipa ile-iwe ọfẹ ya wa lori, o ya ni lara, ọrọ nipa ofin atọwọda ti o ni ka ma sin ohun ọsin bi ewurẹ tabi aguntan nitori awọn arugbo ati alailera ki wọn le ma ri ohun tọju ara wọn jẹ ọrọ atata li eti gbogbo wa, nitori oloye fihan pe ko yẹ ki enia mọ ti ara rẹ nikan.

Alaye olotu Ijọba yi nipa owo ori wọ ni leti pupọ, o fi ye ni pe bi ti ẹnikan ba pọju bi o ti lagbara lọ, ki oluwarẹ kọ iwe pẹlu alaye ti yio fi han gbangba pe owo na pọju agbara on. Bakanna si ni fun owo onipo, ọpọ ti ko ni ọna owo, ti o si ni gbese ti o jẹ pẹlu, ẹku kaka ni o fi njẹun ni nwọn igba ti ire oko ko dara ni oṣelu ti bu owo nla fun lati san, ọgọrọ ninu wọn ni o si kọwe ti wọn ni ki wọn sa san owo na ṣa ni lai wa idi bi o pọju nitotọ. A dupẹ lọwọ Olotu pupọ fun alaye yi nitori bi enia ṣe nsan igba pọun laini inira nibẹ ni ọpọ ti nsan pọun meji pẹlu inira.

Olotu ni ki a to yan enia ka ma gba ẹbun tabi agbatẹlẹ, o si kilọ fun awọn ti wọn fẹ di oṣelu ki wọn yẹ wọ ojule kiri lati ma fun enia lowo nitori ibo. O fi ye wa pe arufin ni ẹnikẹni ti o ba ṣe bayi, lẹkan si mo dupẹ lọwọ Olotu.

Ni ọjọ ipade yi, awọn ọba wa de ade pataki wọn wọ aṣọ ti o ba igba mu, o si yẹ gbogbo wa. Ṣugbọn ti a ba fẹ ṣe ipade ti a ba yan awọn ti o yẹ lati wa ni ipo atata, o yẹ ki a tọju awọn oloye si aye tiwọn aifi owo fun oloye jẹ abuku nla fun gbogbo wa.
Gbogbo ẹnyin Ẹgbado, ẹ ku alejo o.

## AWON IWE KOSEMANI

Iwe Adura Akanse 3/6d
Iwe Ilana Esin Ojisẹ nla Muhammad 7/6d
Kurani Esumẹta ti a tumọ si Yoruba 10/6d
Odu mẹrindinlogun 10/6d
Iwe Aniyan a ti Nofila Oru Oṣu Awẹ 5/6d
Iwe Egbogi Ajẹbidan 20/-
Itan Aladun 3/-
Gbedegbẹyọ Hausa 3/-
Ajiran Ilu Oku 3/-
Itumọ ala kikun 5/6d
Iwe Owe Yoruba 3/6d
Psalmu Isẹgun Ajẹ ati aiye 17/6d pẹlu Turari lọfẹ
Iwe Itumọ Ala ati Ami Ara 3/6d
Afọṣẹ Iṣẹdalẹ Yoruba ati Psalm Ajẹbidan 2/6d

Akiyesi:- Ọpọlọpọ onibara wa ni ko mọ ile-iṣẹ wa ni Mushin, a fi eyi si eti igbọ wọn pe ki wọn ma lọ ra POSTAL ORDER ni POST OFFICE pẹlu Stamp 1/- ki wọn fi ranṣẹ si wa, nwọn yio si ri ọja wọn gba kiakia.

Fi owo ati Stamp 1/- ranṣẹ fun gbigbe ọja rẹ pada
J.O. SHOYINKA c/o Post Office Ebute Mẹtt
Tabi
8, Ojo Road (Oduabọrẹ) Mushin,

## AWON AKEKO ENIA DUDU SE IRAN-LOWO NIBI IFIHAN ATOM NI U-K.



Awọn akẹkọ enia dudu ni University Durhan ṣe iranlọwọ nibi ase ti a ṣe fun awọn ọmọ ile-ẹkọ ati awọn agbalagba nibi ifihan Atam ti a ṣe ni King's College, New Castle upon Type ni England.

Awọn meji ti o wa ninu aworan loke yi ni Ọgbẹni William Young, (ara Saro) ati Ọgbẹni Mammam Sule (ara Ankpa Nigeria). Ọgbẹni Young ti wa ni ilu Oyinbo lati ọdun mẹta sẹhin. O jẹ akẹkọ Physics ati mathematics. Ọgbẹni Sule jẹ akẹkọ Engineering, awọn mejeji si jẹ ọmọ ẹ g b ẹ African Society of King's College ti Durham University.

## Idahun Si Oro Mokadamu

O BẸRẸ LATI OJU EWE KEJI

yato si ẹsin pupọ. Ni igboro Eko ti o jẹ ilu nla, ọmọ Kiriyo ma nlọ si Asaruden ati Amadiya Schools besini wọn ko ma di imale bẹsini awọn ọmọ imale ma nlọ si Batist Academy ati C.M.S. Grammar School ati bẹbẹ lọ, bẹni kosi ẹniti nwon fi ipa mu lati di Kiriyo. Bẹsi, ni nipa isin igbagbọn awọn ọmọ Okeya komọ to ara Eko. Nigbati ẹsin Islam pẹlu awọn ọmọ Okeya koni imọ to ti awọn ara Eko nitorina ki ẹ jẹki a wo apere awọn ti nwọn laju ti oye ye nipa ọrọ ti isin ati ti ẹkọ aiye yi kogbọn ki a si dẹku ima sọ itan asan ti ko yewa to, yala ni ẹsin Islam tabi ti ẹsin Kristi.

Ṣugbọn nipa ti isin awọn agba (barell) ofifo kele ṣe ki nwọn mama pariwo kiri. Nitori awọn ẹlomiran tilẹ fẹrẹ bale de ibi ne bi ẹlẹsin ti o lodi siti ẹni bawa, a ko ba jẹun, a ko gbọdọ ba ṣọrẹ a ko gbọdọ ba da iṣẹ kiṣẹ pọ. Nje ẹmi ifẹ ha ni eleyi bi? Abi awa na kori biti aiye nlọ ion?.

Ninu awọn ti nwọn nṣe akoso ofin Naijiria papa loni nje Kiriyo kosi ninu wọn nje Imale ko si ninu wọn?

Ẹ maṣe jẹki arinrin ajo da nkan miran si arin awa ọmọ onilu o. Ọlọrun yio jẹki ibukun ma wa lori iṣẹ ẹnikọkan ninu ọmọ Okeya. Owo aṣe jere ni gbogbo wa yio ma ṣe. Akoni pade bubur o.

Mo dupẹ aye ti ẹ gba mi o Olotu ọkọ ọba koni ṣa yi nyin lọsẹ o.

Emi ni ẹniti o ni ifẹ Ilu rẹ gidigidi, Ọmọ bibi Okeya ti ki iṣe Arinrin ajo.


## Afose Isedale Yoruba

ATI PSALMU AJEBIDAN

IWE YI WULO NI ONA PUPO

1. Ofọ atata fun Arisiki
2. Ofọ atata fun Madarikan.
3. Ofọ atata fun Itaja
4. Ofọ ti ki jẹki ope ran enia
5. Pslm Ajẹbidan fun Ẹyọnu Ajẹ
6. Psalmu fun Orire
7. Psalmu fun ọja tita
8. Pslm Ajẹbidan fun Madarikan
9. Psalm Ajẹbidan fun idabobo lọwọ Ajakalẹ arun.

Irohin ko to afojuba ti o ba ni iwe yi lowo, o ju Wura ati Fadaka lo.

EYO KAN 2/6
DOSINI 20/-

Fi owo ati Stamp 1/- ranṣẹ si:-

J. O. SHOYINKA
8 Ojo Road Oduabọrẹ
Mushin


## INAKU FI E-ERU BO OJU

OBERE LATI ỌSẸ TI O KỌJA

Bayi ni Ogunji ṣe di olowo ana, bayi ni ẹniti o nla oyin se di eniti o nmu omi kikan, olowo ana si di ẹniti nfi ọpa tanlẹ ki o to ri aje jẹun.

Nignati o ndun fun Ogunji, ọgọrọ ro pe kosi Ọlọrun, bi o ba ndan fun osika ọpọ enia a ma binu bẹ ẹni ba kọkọ la oyin ki o to mọ kikoro ewuro ni yio mọ bi igbẹhin ika ṣe nburu to. Ika a lowo ni ibẹrẹ, ika le bimọ bi ekute ṣugbọn o daju gbangba pe igbẹhin ika. egbe on osi ni ẹniti o ba si da ilẹ, dandan ni pe ki ilẹ da ẹjọ.

Lati Ọwọ
Afọlabi Ọlabimtan.

Mo-bi-mo-bi ọmọ koko, kaka ka bi ẹgbawa ọbun, ba bi ọkan ọga o to. Deoye fi aiye silẹ pẹlu ọmọ kan ati oyun ekeji ninu iya rẹ. Ko mọ bi igbẹhin oun ṣe leri ṣugbọn o ni igbẹkẹ le ninu ọmọ rẹ kan soso ti o mọ. Deolu papa si ṣe aju baba rẹ ni ẹhin rẹ, o ja ija baba rẹ dopin, baba rẹ ku ṣugbọn baba rẹ ku, Adeoye ku o fi Deolu silẹ Ogunji pa Deoye, ẹru di ti Deolu, ki Odumare jẹ ki ọmọ rere gbẹhin gbogbo wa. Amin

Ọmọde ti ko ba ni iwa rere jẹ itiju fun awọn obi rẹ. Ibanujẹ ti o to iru rẹ fun obi ko wọpọ, sibẹsibẹ bi a ti nṣe itọju iwa ọmọ miran to, ko ni gbọ, ko sa ṣe ti inu rẹ sa.

Tani fẹ ki ọmọ bibi inu on ma wulo ni ọjọ aiye rẹ, afi ki o ma daran, ki o si ma wọ ẹwọn bi ọbọ?

Lati Ọwọ:-
Jacob Fọlọrunsọ Soyinka

## Iwarere Ni Nkan

"Imọran Fun Ọmọde Nipa Iwa Hihu"

Ọmọ ti ko ni iwa rere ko soro mọ nibikibi ti o ba wa. Iwa aibikita ati tani-yio-mu-mi ti o ba nhu ni yio fi han gbangba iru ọmọ ti o jẹ. Efin ni iwa, ko ṣe fi pamọ rara.

Bi ọmọ ti ko ni iwa ba ti ndagba si ni iwakiwa yio tubọ ma wọ lẹwu, yio ṣebi ohun daradara ni on nṣe, yio tubọ jingiri sinu iwakiwa, apa ẹnikan ko ni le ka a mọ. A ma npa lowe pe "Kekere ni a ti p'ẹkan iroko, bi oba dagba tan, apa ko le ka a".

Idi rẹ niyi ti a fi nri ọpọlọpọ wọn ti o ba dagba tan, ti wọn ndi ọmuti, ole ati ẹlẹwọn paraku. Ohun pataki ti o yẹ ka kiyesi ni pe iru iwa ti a ba fi kọra nigba ewe, ni yio sọ bi igbesi aiye olukuluku wa yio ti ri nigbati aba dagba Owe gọsi kan lọ bayi ye "Yiyọ orun ni isọ bi oju ọjọ yio ti ri".

Awọn onilu wa a ma lu ilu wọn pe "O ba lowo ko to sẹkẹrẹ, iwa re ni nkan, Enyin ọmọde e ẹ ki a huwa rere o!

Lọsẹ ti o nbọ ọrọ ti ngo ba yin sọ ni nipa "Iwa afojudi ko dara".

## Omodebinrin Jojolo Jasi Kanga.

Ni ikan bi agogo mẹwa owurọ ni ariwo ta gee ni Ladipọ Street Mushin pe Ọdọmọbinrin jojolo kan ja si kanga, awọn aladugbo sare sihin, sare sọhun lati yọ ọdọmọbinrin ti on ati iku jọ njijakadi yi ṣugbọn ko ṣe ṣe, alanu ọkunrin kan ti o nfi mọto ologere rin li o sare lọ si Post Office lati lọ fonu si awọn ọlọpa panapana, ọrọ ti a gbọ jẹnu awọn aladugbo ibẹ ni pe ọmọ yi ti wa ninu kanga ti to iṣẹju marundinladọta ki awọn ọlọpa to de, kiamọsa ni awọn ọlọpa dé, wọn se iṣẹ wọn gẹgẹ bi iṣẹ, wọn si fa ọmo na yọ ṣugbọn a ko le sọ bi o ku tabi oye—Iṣẹ ti awọn ọlọpa ṣe wu mi lori o,

A bẹ awọn Wolewole Mushin ki wọn ma ṣiṣẹ wọn dada lati ma ri pe awọn kanga ti wọn ngbe ni Mushin ni ideri dada, ki iku ojiji yi le dawọ duro. Mo ba ẹnyin ẹbi ọmọ yi kẹdun, Oluwa po ni jẹki ẹ ri iru eyi mọ o.

E MA KA IWE IROHIN IMOLE

